# AJINDE JESU

## Johannu 19:31-42; Matteu 27:62-66; Johannu 20:1-31

## ẸKỌ 14 --- FUN AWỌN ỌDỌ

**AKỌSORI: "Njẹ nisisiyi Kristi ti jinde kuro ninu okú, o si di akọbi ninu awọn ti o sùn" (1 Kọrinti 15:20).**

### A Ṣe Ileri Irapada

Ọlọrun ti pinnu lati igba iṣẹ̀dálẹ ayé pe lọjọ kan Jesu yoo wá si ayé lati fi igbesi-ayé Rẹ̀ kọ ni bi o ti yẹ ki a maa ṣe; ati pe Oun kò le ṣalai ta Ẹjẹ Rẹ̀ silẹ ki O si kú ki a ba le dari ẹ̀ṣẹ awọn eniyan jì wọn ki wọn si le lọ si Ọrun.

Jake jado gbogbo Majẹmu Laelae ni awọn wolii ti sọ̀rọ nipa akoko ti Jesu yoo wá lati ṣetutu fun ẹ̀ṣẹ awọn eniyan; ati nitori awọn wolii naa gbagbọ́ pe Jesu yoo wá, Ọlọrun fi ẹ̀ṣẹ awọn naa jì pẹlu; nigba ti wọn si kú wọn lọ si Ọrun rere. Ọlọrun sọ fun awọn wolii ohun ti wọn ni lati sọ, eyi ti o mu ki o jẹ ootọ gan an; bẹẹ ni ohun gbogbo ṣẹ bi o tilẹ jẹ pe a ti sọ asọtẹlẹ wọn ni ẹgbẹẹgbẹrun ọdun ṣiwaju. (Wo iye itọkasi ti iwọ le ri ninu ẹ̀kọ́ yii si awọn Iwe Mimọ́ ti Majẹmu Laelae, gẹgẹ bi Orin Dafidi 22:16; 69:20; Isaiah 53:4-7).

Ni tootọ kò dùn mọ Ọlọrun ninu nigba ti ọkunrin kin-in-ni Adamu, dẹ́ṣẹ̀, bẹẹ ni kò wu U nigba ti awa naa ba dẹ́ṣẹ. O ti sọ fun wa pe a ni lati jiya fun ẹ̀ṣẹ wa, bi kò ba si ṣe pe Jesu ti kú fun wa gbogbo wa ni i ba lọ si ọrun apaadi. Ṣugbọn Ọlọrun fẹ wa to bẹẹ ti O fi rán Jesu, Ọmọ Rẹ̀ kan ṣoṣo, Iṣura ti o ṣe iyebiye ju lọ ni Ọrun, lati wá jiya fun wa. Jesu jẹ ki awọn eniyan tutọ si Oun lara, O jẹ ki wọn fi ade ẹ̀gún de Oun lori, ki wọn fi paṣan na Oun, ki wọn si sọ ọ̀rọ iwọsi si Oun, bẹẹ ni kò si fesi. O bẹrẹ lati gbé agbelebu ti o wuwo naa, ṣugbọn awọn ọmọ-ogun mú ki Simoni ara Kireni rù u fun gbogbo iyoku irin naa lọ si ori oke.

### Ki A Ba Le Yè

Nigba ti agbajọ awọn eniyan-keniyan de ori Oke Kalfari, wọn tẹ́ Jesu sori agbelebu wọn si kàn iṣo mọ ọwọ́ ati ẹsẹ̀ Rẹ̀ lati de E mọ agbelebu naa. Nigba naa ni wọn gbe agbelebu naa ró, Jesu si so rọ̀ nibẹ pẹlu Ẹjẹ ti n ṣàn jade lati ọwọ́ ati ẹsẹ̀ Rẹ̀. Lẹyin igba diẹ, ọmọ-ogun kan fi ida rẹ̀ gún iha Jesu, Ẹjẹ ati omi si ṣàn jade. Nigba ti omi ṣan jade eyi fi hàn pe gbogbo Ẹjẹ naa ti jade tán – a ti ta gbogbo rẹ̀ silẹ fun ẹ̀ṣẹ wa. Nisisiyii a le tọ Jesu wa ki a si bẹ̀ Ẹ lati wẹ ẹ̀ṣẹ wa nù pẹlu Ẹjẹ nì ti a ta silẹ lori Kalfari. Jesu kò ha ṣe wa loore?

O mu ọkàn Ọlọrun bajẹ pupọ pe awọn eniyan ṣe ibi si Jesu to bẹẹ, nitori naa O mu ki okunkun bo ori-ilẹ laaarin ọ̀sán gangan. Ilẹ ṣokunkun fun wakati mẹta -- iṣẹlẹ si wà pẹlu. Eyi dẹruba awọn eniyan naa, awọn kan ninu awọn alaigbagbọ si wi pe, "Lõtọ Ọmọ Ọlọrun li eyi iṣe."

### A Tẹ́ Jesu Sinu Iboji

Awọn Ju kò jafara lati pa Ọjọ Isinmi mọ́. Iwọ le rò pe, lẹyin gbogbo ikà ti wọn ti ṣe si Jesu, wọn kò ni ẹ̀sin kan lọ titi. Ṣugbọn awọn eniyan wà lonii ti o n wi pe Onigbagbọ́ ni awọn i ṣe ti wọn si n purọ, wọn n jà, wọn n lọ si ile sinimá, wọn si n ṣe nnkan pupọ ti Jesu kò fẹ ki wọn ṣe.

Nitori Ọjọ Isinmi sunmọ tosi, ti Ofin si ti wi pe ẹnikẹni ti a ba ti so kọ́ sori igi kò gbọdọ wà nibẹ kọja ọjọ naa, awọn Ju wi fun Pilatu pe ki a ṣẹ́ ẹsẹ Jesu ati ti awọn olè meji ti a kan mọ agbelebu pẹlu Rẹ̀ ki wọn má ba sálọ lẹyin ti a ba ti sọ̀ wọn kalẹ̀ tan. Nigba ti awọn ọmọ-ogun de ọdọ Jesu ti wọn si ri pe O ti kú, wọn kò ṣẹ́ ẹsẹ Rẹ̀. Niwọn ọpọ ọgọrun ọdun ṣiwaju, Dafidi ti sọ nipa Jesu pe, "O pa gbogbo egungun rẹ̀ mọ́: kò si ọkan ti o ṣẹ́ ninu wọn" (Orin Dafidi 34:20). Ọlọrun kò jẹ ki nnkan kan ṣẹlẹ si Jesu ju nnkan ti Oun ti sọ fun awọn wolii pe yoo ṣẹlẹ̀.

Josẹfu ara Arimatea jẹ eniyan rere kan ti n reti ijọba Ọlọrun, oun ko si sọ̀rọ̀ kan lòdi si Jesu nigba ti a n yẹ ẹjọ Rẹ̀ wò. A ko gbọ́ ohun kan nipa rẹ̀ ṣiwaju akoko yii, ṣugbọn nisisiyii o fi igboya tọ Pilatu wá, o n tọrọ okú Jesu ki oun ba le sin In. Josẹfu ni iboji titun kan ti ko jinna si ibi ti a kan Jesu mọ agbelebu, ninu eyi ti o gbe tẹ́ Ẹ si. Nikodemu lọ pẹlu rẹ̀ o si ba a di okú Kristi ninu aṣọ ọ̀gbọ mimọ́, wọn si ra nnkan oloorun didun ti o niye lori lati fi di I, gẹgẹ bi àṣa awọn Ju. Josẹfu jẹ ọlọrọ̀ eyi ti o mu asọtẹlẹ Isaiah ṣẹ pe, "O si ṣe ibojì rẹ̀ pẹlu awọn enia buburu (awọn olè), ati pẹlu ọlọrọ̀ ni ikú rẹ̀."

**Kò si Iboji ti o le Dá A Duro**

Awọn Farisi ti wọn ti kàn Jesu mọ́gi ranti pe Jesu ti wi pe Oun yoo tun jinde. Wọn tọrọ àye lọdọ Pilatu lati ṣe iboji naa daju ki a ma ba gbe oku Jesu jade. Josẹfu ti gbé okuta nla kan soju ẹnu-ọna, nisisiyii awọn Farisi ati awọn alufaa wá fi edidi di i wọn si yan iṣọ sibẹ lati ma ṣọ ọ. Ṣugbọn ete ọmọ eniyan lati di iṣẹ Ọlọrun lọwọ ti jẹ asán to! "On o si fi ẽmi ète rẹ̀ lu awọn enia buburu pa" (Isaiah 11:4). Ranti akoko ti a fi Daniẹli sinu ihò kiniun, a fi okuta di ẹnu-ọna ihò naa, a si fi oruka edidi ọba di i; ṣugbọn eyi kò sé angẹli Oluwa mọ́ ita. Angẹli naa lọ taara pẹlu Daniẹli o si di awọn kiniun naa lẹnu.

Nigba ti akoko to fun Jesu lati jinde, O jade taara bi ẹni pe kò si nnkan kan ti o dè E. O ni ara ologo pẹlu eyi ti O fi le wọle nigba ti awọn ilẹkun ba wà ni títì. Nigba ti Jesu ba wá lati mu awọn eniyan Rẹ̀, awọn ti o ba mura tán lati bá A lọ yoo ni iru ara kan naa, wọn o si gba orùlé kọja (bi wọn bá wa ninu ile) bi ẹni pe ko si nibẹ; wọn yoo si lọ wà pẹlu Jesu.

Jesu ti sọ fun awọn ọmọ-ẹyin Rẹ̀ nigba pupọ pe Oun o jiya Oun o si kú, ati pe Oun o tun jinde. Ṣugbọn wọn kò fẹ ki nnkan wọnyii ṣẹlẹ si Jesu, nitori bẹẹ wọn kò tilẹ gbà wọn rò rara. Jesu tilẹ ti sọ fun wọn bi Oun yoo ti pẹ́ to ninu iboji -- ọsan mẹta ati oru mẹta. Awọn Ju a maa ka apa kan ọjọ kọọkan si ọ̀sán kan ati oru kan, Jesu si wà gẹgẹ bi okú lati apa kan Ọjọ Ẹtì (Friday), Ọjọ́ Abamẹta (Saturday) ati Ọjọ Oluwa (Sunday).

Nigba ti Jesu jinde, O já idè ikú. O jẹ́ iṣẹgun ribiribi, ilẹ si mi titi lati fi hàn bi o ti ṣe ribiribi to. O fi hàn wa pe iye wà lẹyin ikú. Ni akoko kan ti O n sọ fun awọn ọmọ-ẹyin Rẹ̀ pe Oun n lọ kuro, O wi fun wọn pe Oun o tun wà laaye, ati pe "nitoriti emi wà lãye, ẹnyin ó wà lãye pẹlu." Paulu sọ fun ni pe Kristi ni akọbi ninu awọn ti o sùn (tabi ti o kú), nigba ti O ba si pada de gbogbo awọn ti i ṣe ti Rẹ̀ ni yoo jinde pẹlu ara ologo lati tun wà laaye (1 Kọrinti 15:23).

Lẹyin ti Jesu fi iboji silẹ angẹli kan sọkalẹ wá lati yí okuta naa kuro ki awọn ọmọ-ẹyin ba le ri i pe Jesu ti lọ. Nigba ti awọn oluṣọ, ti wọn ṣebi wọn jẹ́ ogboju ri angẹli, ẹ̀rù bà wọn to bẹẹ ti wọn dabi okú, wọn kò si le mira. Nigboose wọn lọ, wọn si sọ ohun ti o ṣẹlẹ fun awọn alufaa, awọn alufaa si fun wọn ni owó pupọ lati sọ fun awọn eniyan pe awọn ọmọ-ẹyin Kristi ti ji ara Rẹ̀ gbé lọ ni oru. Wọn kò fẹ ki ẹnikẹni gbagbọ́ pe Jesu ti jinde kuro ninu okú. Eyi fi wọn hàn bi alai ni laari oluṣọ. Ṣugbọn awọn ẹlomiran fẹrẹ le sọ ohunkohun nitori ati rí owó gbà.

Ọkàn awọn ọmọ-ẹyin wuwo nigba ti wọn wá sibi iboji lati fi ororo ikunra kun ara Jesu. Ani nigba ti wọn tilẹ ri iboji ofifo wọn kò gbagbọ́ pe Jesu ti jí dide. Ṣugbọn angẹli meji fara hàn, awọn ẹni ti o rán wọn leti ohun ti Jesu ti wi pe: "A ko le ṣaima fi Ọmọ-enia le awọn enia ẹlẹṣẹ lọwọ, a o si kàn a mọ agbelebu, ni ijọ kẹta yio si jinde" (Luku 24:7). Nigba ti wọn ranti ọ̀rọ wọnni wọn fi ayọ̀ nla sare lọ sọ fun awọn ọmọ-ẹyin iyoku pe Jesu wà laaye. Maria Magdalene ni o kọ ri I; lẹyin naa O fara hàn niye igba, nigba miiran fun awọn eniyan diẹ ati nigba miiran fun awọn eniyan pupọ lẹẹkan naa. Johannu sọ fun ni pe oun wà nibẹ oun si funra oun ri gbogbo nnkan wọnyii, o si n jẹri pe otitọ ni wọn.

### AWỌN IBEERE

1. Ki ni ṣe ti a kò fi ṣẹ́ ẹsẹ Jesu?
2. Ipa wo ni Nikodemu ní ninu isinkú Jesu?
3. Nnkan mẹta wo ni wọn ṣe lati daabo bo iboji Jesu?
4. Ta ni ẹni ti o kọkọ rí Jesu lẹyin ti O jinde?
5. Iwọ ha rò pe o ṣe e ṣe fun wa lati ni igbala bi o ba ṣe pe Kristi kò kú?
6. Awọn ọrọ Jesu ti o wi pe, "Alafia fun nyin" ni a sọ ni ẹrin mẹta laaarin ọjọ mẹjọ. Ni akoko wo ni a sọ wọn?